Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Akiyesi Patiki**

A fiwe yi se ikede si awon Asoju Iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, eniken ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa, o ge lejo, ako si ni fi iwe irohin ranse si enibe mo.

VOL. XI No. 617. LAGOS, SATURDAY, MARCH 28 — APRIL 3, 1959. KOBO MEJI (2d).

# Iwadi Oro Lori Awon Obinrin Oloja, Eri Saratu King Ko Muro

EKO Noru Alowonile okan ninu omo egbe N.C.N.C so pe, wa posu owo ranse si Town Council nitoripe on na paapa nfe iso fun awon iyawo on meteta. Ibeni Ogbeni Beyioku ti so fun Rapson oluwadi oro pe, on ni oro lati bere lowo Alhaja Ashabi Awe.

**BI AJA KO NI EKUN RI!**

Nibi iwadi oro awon obinrin oloja, Ogbeni Beyioku so fun Oluwadi oro Ogbeni Rapson wipe, awon obinrin ti o ba fi ara mo ti egbe Afenifere (Action Group) nikan ni awon obinrin nwonyi ngba laye lati mata oja larin won.

Alhaja Asabi Awe dahun pe, nibiti awon obinrin gbe ntaja nibi gbogbo, ko si edekoyede kan larin awon obinrin oloja, olukuluku nse egbe ti o ba wu u, tabi esin ti o wu, inikan na ni gbogbo wa nkojo po lati ma taja, enikini ko di enikeji lowo.

Ogbeni Beyioku tun bere lowo Asabi Awe pe, kilofa ti o fi je wipe nigbogbo igba ti Oloye Awolowo ba wa sileyi, ti gbogbo awon Obinrin oloja nu yio fi ko oja sile lati lo pade re, sugbon nigbati Dr Azikiwe tabi Sardauna Sokoto tabi Endeley ba wa si Eko ti awon obinrin na ko fi ni mo pe eni ola kan wo ilu.

Ibe ni Ogbeni Rapson ti so pe on ko ni aniyan lati pe Alhaja na wa dahun si ibere ti Ogbeni Beyioku mu wa. Obinrin kan Omidan Saratu King ti o je akowe Muslim Party, ko iwe eri re repete, sugbon Oluwadi bu ete lu iwe eri re pe, ko moyan lori.

(N.C.N.C.) ati awon ala- ... won fi adura se iranti baso ... Alhaji mimo ti Ologbe... run na.

Lehin is... adura ninu ... ni Ibadan Mosalasi ka... to ni isowo- ni awon enia ...gogo meji isowo ni dede ... oji Alhaji osan lo si ori ... ti soro na nibe si awon ... Ologbe iyanju fi bu ola fu... bi ti a na. Kosi oja tita ta nilu Ibadan lojo na.

## Ibadan Se Iranti Adelabu



IBADAN—Ni ojo kedogbon osu March, 1959, ti ise ayajo ojo ti Alhaji Ghadamosi Adegoke Adelabu pade agbako iku gbigbona re l'ona Ode Remo nitosi Ilu Shagamu ni awon egbe Alakuko

## Dr Mbadiwe Pe Dr Azikiwe Nija

ABA—Dr. K.O. Mbadiwe ti o je asiwaju egbe Democratic Party of Nigeria and Cameroon lo pe Dr Azikiwe, asiwaju egbe N.C.N.C. ni ija wipe bi Azikiwe ba gbagbo wipe on ni iye mi lori, ti o ba igbimo ru, ki nwon jojo wa dibo yan awon igbimo Eastern House of Assembly.



Dr. Mbadiwe so pe, bi Azikiwe ba gba be, o da on loju wipe, egbe N.C.N.C ko ni gbo'run ijoba Ila-Orun mo.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEWYORK, PARIS HAMBURG.

# ELETI - OFE

YẸA-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 617. SATURDAY MAR. 28 - APRIL 3, 1959.


# Jesu Ayorunbo Tun Ji Dide

Ni kutuhai owurọ ọla ni ariwo ayọ yio ti ma ta pe "O jinde" "O jinde" Tani ẹniti o jinde na? Kristi Atohunṣe lo jinde, Kristi Alagbalajaiya-jaiya lo jinde, Kristi Afifẹ-fanimọra lo jinde kuro ninu oku. Ọjọ ti o tun ju ọjọ yi lọ fun gbogbo Onigbagbọ kosi ayafi ọjọ ibi rẹ.

Irufẹ ajinde Kristi ti ao ke'bosi rẹ lowurọ ọla yi ki iṣe ajinde ti ara oku, ara eru fun eru, erupẹ fun erupẹ, ẹkuru fun ẹkuru, bikoṣe ajinde ti ẹmi. Boya a leri enia ti yio ma jiyan wipe, bi o ba jẹ ara ẹmi ni Jesu gbe wọ nigbati Maria Magadaleni fi ri ninu ọgba ti a sin'ku rẹ si kini ṣe ti ara ẹmi na fi jọ ara'yara bẹ? Esi irufẹ ibere yi ni wipe, ara ẹmi ko yatọ si ara'yara, bikoṣe ohun ti a fi ṣe ekinni lo yatọ si ekeji.

Gidipa, a ṣebi St. Paul ti sọ fun wa wipe ara'yara mbẹ ara ẹmi si mbẹ, dajudaju, ara ti Kristi gbewọ ni ayajọ ọjọ ọla jẹ ara ẹmi eyiti o fi goke re ọrun lẹhin ogoji ọjọ lẹhin ajinde rẹ. Jesu kole gbe ara erupẹ lọ si isalu ọrun nitoripe ara ati ẹjẹ ki yio le jogun ijọba Ọlọrun, bẹni idibajẹ ki yio le jogun aidibajẹ.

Njẹ ẹnyin ara, ẹku ewu ajinde, ajinde ara yio ma jẹ fun gbogbo wa, amin, apa ekute ile kole ka-'wusa, nibi yiyi kiri lo mọ. Apa araiye ko ni ka to-lori-telese wa o. Amin, aṣẹ.

Ẹku ewu ọdun ! ! !


## Imoran Fun Enyin Abiymo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA, o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otu u, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọ ja n' asiko hin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)

18, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Enyin Obinrin Eko, E beru Oluwa

Mo dupẹ lọwọ Olotu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ fun aye ti o gba mi lati sọ awọn ọrọ wọnyi, ọwọ rẹ yio ma ma roke o ni rija ọmọ araiye o. Amin. Nigba lailai ti awọn iya wa ba wọ buba, wọn a ro aṣọ mọ igbaiya wọn, (Their breast) wọn yio we gele iborun wọn a si pele pẹlu, ṣugbọn asiko ti awa ni aiye isinsiyi ko si ibẹru Ọlọrun Ọba ni ọkan olukaluku wa mọ a fi ki a ma ṣe nkan ti Ọlọrun Ọba kọ fun wa.

Ẹ wo ode Eko wa ti isisiyi gẹgẹbi ilaju wa ti o ko iwa ibajẹ ba wa ọrọ alaye mi ko ba awọn ti o wọ aṣọ kaba yẹri tabi Ghana style wi, awọn ti mo ntọka si ni awọn ti won nro aṣo ilẹ wa ti wọn nwo ẹwu buba fẹlẹfẹlẹ (Nylon) bawonyi-Ekini wọn yio mu (Corset) figbe ọyan soke nwọn yio wọ ṣimi wọn a si wọ buba le lori Ekeji wọn Ie wọ ṣimi nikan pẹlu buba Ẹketa won si le lo (Corset) igbe ọyan soke nikan ki nwon si wọ buba si Ẹkẹrin. wọn

(Wo yoku loju ewe karun.)

# Revised Passenger Services

## (Effective 1st April, 1959)

Alterations in timings of Limited and Mail train services are seperately advertised. Other alterations are as follows.

LAGOS — ABEOKUTA — IBADAN

The 08.00 hrs. train from Lagos will not run

The 06.05 hrs. Lagos Abeokuta train will not run beyond Abeokuta (arr. 09.50 hrs) on Sundays

X X X

IBADAN — LAGOS — IBADAN

A new service is being introduced

Ibadan dep. 06.30 hrs.)
Lagos arr. 13.20 hrs.) daily except Sundays

Lagos dep. 17.15 hrs)
Ibadan arr. 23.50 hrs) daily except Saturdays


## Tani o si ile Yinyin na?



"Emi ni" Bẹni Sammy Sparkle wi

Asiko to fun STAR'

# Itan Ajapa Ati Ekun

Nigbati ẹkun da Ajapa duro o nfẹ gbẹsan iku baba rẹ lara ajapa, o fẹ mu silẹ de nkan ti o nle bọ wa. Nibiti ẹkun ngbe dunnu fun Ajapa lọwọ ni awọn igba turuku yo lokere Ominu wa bere si ko ekun, wipe iru kiniyi, Ajapa ko fi gba kan gbẹkẹle ọmọ ẹkun, ki awọn igba to de ajapa ti lọ ti ẹkun ko si mọ.

Ẹkuu ti foju da ori igi ti yio gun, nigbati igba ku sata bi ẹsẹ mẹta ni ẹkun ta mọ igi, o rope ọwọ yio tẹ Ajapa-firi firi ni awọn igba na nle Ajapa lọ titi o fi pade Ajanuku ti o daa duro, ṣugbọn ko fẹ duro. Erin ṣeleri fun pe bi o ba tiri ẹranko bi Erin ki o ma fi ọkan balẹ.

Koiti sọrọ yi tan ti oruku awon igba na so lala soke ti nwon ulepa ajapa bọ. Nigbati Erin foju kan wọn o bẹrẹ si gbọn riri, oyidi si awọn igba ti o mbọ. o ya iso lu n o tobẹ ti oruku iso na ti awon igba na pada si ẹhin, laipe awon igba tun dẹhinbo bẹni Erin ba ya lu igbo.

Bi Ajapa ti tun nsare lo o pade ẹran agbo kan kuru ti o si nfi jojo wole. Agbo na pe ajapa o wipe kilode ti e fi nsare bayi ajapa si ko gbogbo ejo na o rohin fun agbo Agbo dahun pe ore ti o ṣe fun mi nijosi, o ya ti ngo ṣesan re fun o loni, bo si ehin mi

Tohun tenu awon igba turuku yo lokere, nigbati nwon gborun ajapa ere won tunbo wa posi A gbo wa tadi mo ehin o fi iwo le fya igba ti o wa niwaju o la o la si meji gbereẹgede, o tun fi iwo le ekeji. ẹketa ẹkẹrin titi o fi fo gbogbo awon igba na ṣan. Inu Ajapa dun ṣugbon riro ti Ajapa ro mo ẹpon agbo lojo na lo jẹki ẹpon agbo san silẹ titi di oni.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ofe.

# Eniti Ajija Gbe Lo Pada Wale

OSHOGBO. Ọkunrin kan ti o njẹ Oṣidalu ni a gbọ wipe, o bẹrẹ si ojojo o si ti wa lẹnu ojojo na ọjọ pẹ diẹ

Ni owuro ọjọ kan ni nwọn fẹ ku ninu ile, nwọn wa a, nwọn ko ri, ni awọn enia rẹ ba lọ rohin fun awọn ọlọpa. Ọdun na jẹ ọdun 1930. Ọmọ kekere ti iyawo okunrin na bi sọwọ ti dagba, o si ti bimọ a ya fi bi ọkunrin na ti wọle de ti o mbere ọmọ rẹ ọkunrin ti o njẹ Dele.

Dele papa ko mọ baba rẹ, ayafi nigbati nwọn lọ pe iya Dele wa. Nwọn dimọ ara wọn, nwọn yọ. Nigbati awọn Oniwe irohin lọ bere ọrọ lọwọ rẹ. O dahun pe bi Ajija ti gbe on, o gbe on lọ sidi igi ibẹpẹ. O si ngbe onjẹ wa fun on. Gbogbo awọn ti o nwa on kiri ni on nwo kedere. Ibẹpẹ ni on njẹ fun igba pupọ.

Ọpọlọpọ ede lo kọ on, ede pupọ ni on si gbọ ko si egbogi ti on ko mọ ko si alijannu ti on ko le pe, ko si s'amodi ti on ko le wo san.

## OHUN ARO FNU IKU OGEDENGBE

O se! o po! iku mu enire lo, ile si fi jẹ. Ha! o mase o, ile nje eniti o tobi. Iku ogun lo npa akin, iku odo lo npa omuwe, iku yi were opa Ogedengbe Ikare mi titi

"Sa wo o bi awon alagbara ti nsubu" Bode Thomas Balogun Oyo da, iku se be e. o ma lo. Ọmolodun nko, o sile Ọlorun wo, Ojike da, o ba won rin irin ajo na, Nwapa nko ? o ba wa lo, ha! ile nje eniti o tobi.

Awon ti o ba ku ni di ohun ala, ko ku, gbe. bi ile ba tile fi eje won mu, ti orun si yan ori won gbe, ko da ki a tile kan ori won mo enu bode, sibe, iranti' won yio wa titi lai. Nigbati a ba de busun won, ao si ma so o lati irandiran pe awon lo se eyi.

Ẹmi won ko ni ku, Ọdun le yi bori Ọdun, ki osu si le bori osu "Ejo nigboro." Herbert Makoli da ? a ko ni gbagbe nyin Nigba kokan ti a ba nranti ojo idande wa ao ma ranti enyin to ti jagun na ti e si fi ba ogun lo. E sun re!

# Eniti Ko Jeki Ogun Ja Nile Egypt



Ẹniti a nwo yi ni Sir Anthony Eden ti ogun ori oye Prime Minister tilu Gẹsi lẹhin ti Ọgbẹni Winston Churchill gba iṣinmi kuro lẹnu iṣẹ iṣelu tan, on ni ẹniti o da ija ogun ilẹ Egypt ru, nigbati nwọn ti dira ogun silẹ lati ba Israẹli jagun, ti ogun na si rọ'pa.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbeni Macmillan ti o mbe lori oye Prime Minister ilu Gesi loni, on lo sọ wipe, gbogbo nkan ti Sir Anthony Eden ṣe nilu Egypt dara pupo, ti ko jeki Egypt ati Israeli ba ara won ja ogun. Nitorina, on fi mọ ohun ti o ṣe na ara

# NISISIYI !

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWỌN ONIṢOWO

## THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

## NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa re ni ao ṣe fun yin lọfẹ.


## Moto Pa Atun Agogo Se.

Agbọ irohin wipe, okunrin kan ti o njẹ Rufayi Owodunni ti o ntun agogo se ni Idi-oro lojọ Alamisi. Owedunni je ojulumọ fun epọ awọn Olotu inu Moto akero, a gbọ wipe, o lo duro ni ibuso moto ni adugbo Alakara lati wo moto ti o o nlọ si Eko.

Tohun-tenu na, beni moto akero kan ti o je ti Benson L.D. 3866 yo lokere okunrin na lero wipe, moto na yio duro ni Alakara, sugbon ko duro o nfe kojalo ni.

Eyi ni Rufayi Owoduni ri ti inu re dun, nitoripe ko ese oni tab ana lo ti oro mo moto be gege bi adan, sugbon lojo buruku yi bi moto na ti nsare koja ni Rufayi Owodunni ba fo mo moto Benson, beni owo re ja kuro lara moto yi agbari okunrin na ni moto re mole koja, o si fo gbogbo mudun mudun inu ori re.

Jare Oluwa, lowo iku gbigbo na ati iku ojiji, oluwa rere gbawa.

## Ko Sibiti Ese Ko Si

DAKAR. Ibo ti nwon di nilu Siniga (Senegal) ni ọjọ 23rd osu March 1959. Ogunlogo enia lo fi ara gbogbe ninu awon ile idibo, tobe ti nwon ni lati ranse pe awon ṣọja Faranse lati wa dero si.

## ENU OFORO LO NPA OFORO.

Lati Owo Eso

Odu ifa kan sọ bayi wipe, Enu pa ẹlenu, orọ pa ọlọrọ a difa fun Lẹmikan lọjọ ti o nlọ si oko igbamu aiye, a ni ki o fi ada ọwọ re rubo ki o ba le da eti kan ti o mbe lorun re kuro. Lemikan gbo, ko tubo, ko setutu o se eti gbonran si ebo, o se aran igbo si esu.

Ni ojo yi, bi orunmila ti nda ifa re lowo ninu ile kan nile Ife bi o ti da ifa re sile, beni Lemikan ndagere pe on nlo si oko. Orunmila ni ki o pada wa fi ada owo re rubo ki o to lo si oko, para ti Lemikan ma dahun, o ni enyin baba ki baba nwonyi ese ti enyin ko nronu wo ki e to ma sọrọ, o gbo nisisiyi nigbati mo so wipe, mo nlo si oko, bi mo ba de oko tan, se ekanna mi ni ki nfi roko? O bu Ọrunmila dara-dara ki o to gba ọna oko re lo.

Ki o to to ojo na, awon Onisunmomi ti gbe ogun wa ja oko awon ara Ife, agbe ti nwon ba ninu oko re, nwon be agbe na lori, nwon fi ori re p'ale sinu oko Lemikan. Nigbati Lemikan de inu oko re, ko se akiyesi ori gbigbe ti nwon fi p'ale sinu oko re, nitosi ori gbigbe yi ni ope kan wa. Bi Lemikan ti de, kere lo tagun igi oke yi, ti o si bere si da emu lori ope na, emu wa bere si ro sori ori gbigbe na. O mase o, Agbe elemu ogogo. Lemikan wo fere wipe, tani nsoro? O wo yi ka kiri, ko ri enikan, o wa sokale lati lo gun ori igi ope miran, beni ori gbigbe tun wipe, efun mi emu die towo.

Lemikan yi ju pada o ri ori gbigbe, o ni iwo taniyen ? ori na dahun pe emi ori elemu ni Lemikan kigbe wipe, ha ! ori gbigbe nsoro, o si, o kori si ile Olofin. Nigbati o de ile Olofin, o wipe Kabiyesi ! mo ri ori gbigbe ti o nsoro. Olofin bu si erin o ni jowo ma lo Ọkunrin yi jeki nfi edo leri ororo, Para ti Okunrin yi ma dahun, o wipe bi nwon ko ba ba bee ki oba be on lori. Nigbati iyonu Lemikan po, oba yan enia tele wipe, bi oro na ko ba je be, ki won fi ada owo re be lori.

Awon iranse Ọba tele de ibiti ori gbigbe na wa o so, so, so ori gbigbe na ko soro, o se, se, se, ko soro ni awon iranse Ọba ba fi ada owo re be lori. Bi nwon ti be Lemikan lori tan beni ori gbigbe na ba fohun o wipe, e seun seun, ara ro m si i si i. Ẹnu mi ma ma gbami la o.


E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

L'ỌSỌSẸ O KUN FUN IROHIN ALADUN

# AZIKIWE LODI SI EPO MOTO LILO FUN RELUWE



**Nigbati Dr Aziklwe fi nsọrọ ni ilu Bukuru o so wipe, on ko fi ara mọ wipe ki nwọn Alaṣẹ Reluwe fi edu silẹ ki nwọn ma lo epo moto** (Diesel) nitorpe bi nwon ba se be yio ba nkan je, awon osise ko si ni ri ise se mo, owo ilu yio fa sehin, awon osise ko ni ri ise se dabi alara.

Iberu ni ero yi jẹ lokan on ati awon igbimo on, on si tun fẹ mu imoran kan wa wipe, awon ojogbon le ri epo Diesel lati inu e edu bi a ba po orisi egbogi bi meji mo.

---

ẸNYIN OBINRIN EKO Ẹ BẸRU OLUWA
(O bẹrẹ loju ewe keji)

**le wọ buba fẹlẹfẹlẹ nikan ki nwon ma lo ṣimi tabi (Corset).**

Wọn yio wa ro aṣọ si idi laiko ro mọ igbaiya (Breast) ki ẹnikẹni le ma ri ọmu won bi o ti dara to ni oju wọn. Eleyi jẹ itiju fun wa o si je iwa abuku larin awọn ọkunrin ti o ba pẹya Ọlorun Ọba, Ọmu ti awọn ọmọ yin yio mu ẹ maṣe fi han agbaiye, ki a ma ba ri ibinu Ọlọrun. Ẹro aṣọ yin mọ igbaiya yin ẹ ye fi ọmu yin han kakiri ẹ pa aṣiri ara yin mọ. Ẹ maṣe da aṣakaṣa ti Oluwa ko yọnu si.

Opọlọpọ ni awọn alufa wa ni Onigbagbọ Muslim ati awọn aṣiwaju ijọ Kerubu ati Serafu ti nwọn se iwasu fun wa wipe k'a bẹru Ọlọrun. Aṣa yi jẹ aṣa ti awọn obinrin agbalagba, ati awọn ọmọde gbe danu lati ma fi ọmu wọn han kakiri laiko ro aṣọ mọ igbaiya wọn.

Ẹ BẸRU ỌLỌRUN

---

# Ijoba Si Ile Ifiwe Ranse Si Okitipupa

Lati owo R.A. Orowole Oshatuyi

OKITIPUPA. Oloye S. L. Akintola, nigbati o nsoro nibi saile (£5,500) ile ifiwe ranse ni ilu Okitipupa, niwaju oganlogo enia, awon oba ati awon ijoye so pe, ile ifiwe ranse na ni ijoba (20.0) Apoti iwe Ijoba apapose lo ko ile na fun anfani awon ara ilu Okitipupa.

Nigbati nwon fe si de na, Ogbeni G. A. Bennet to se Alaga, on ni alase gbogbo ile ifiwe ranse ti o mbe ni Iwo Orun. Oba gbogbo enia yo fun ile titun na. O si tun seleri pe laipe ero ti a fi nsoro (Telepone) yio de ibe pelu.

Ninu iwe ikini kabo ti awon ara Okitipupa fi ki i, nwon dupe gidigidi lowo Ijoba apapose, ti o ko iru ile be fun won.

Sugbon ki o ko awon ile if iwe ranse ti o je kekeke be si awon ilu ti o mbe ni agbegbe okitipupa kakiri kio si fun won ni awon akowe ti yio tete le ma mojuto iwe won.

Oloye Akintola dahun pe, ese kiakia ni awon ara ile Nigeria ngbe nisisiyi, igbese won si yara iu ti ilu miran lo. A si ti fa ilu Okitipupa si agbo na gegebi awon ilu nla nla miran. Mo ba gbogbo nyin yo fun ti Post Office Titun ati ero isoro ti yio kan nyin lara lojo aipe.

Die ninu awon enia jankan jankan ati awon gbajumo ti o wa sibe ni Ogbeni O. A. Ajose Oga agba ile ifiwe ranse ti Ibadan W. Willoughly P.R. Wilkinson, D.Milliner, J. H. Jeres Cymbo U.A.C. Okitipupa.

Ogbeni C. B. Okunuga J. O. Latunbosun M. O. Oyediran R.A. Oshatuyi R. O. Adegboye DR. Oji, E.O. Ogundele, J. B Marquis Iyafin L.O. Iyun, Oloye Laleye.

---


Kere o !

**Ati ni orisirisi ogun German to sẹsẹ de, fun oniruru aisan tọkmrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.**

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos




# Irin Ajo Lo Si Meka Ati Medina

(Lati owo Alhaji.)

Bi enia ba fe lo si Meka, A'coko nkan ti oluware ni lati se nipe, yio gba iwe aşe lodo Ijoba "Pass Port" Lehin eyini, oluware yio lo ko nomba ni ibise awon Wole-Wole. Ti oluware ba ti ko nomba tan, Oga tabi Alase ibi ise awon Wole-Wole yio fun ni iwe wipe oluware ti o yege ninu nomba re. oluware yio tun lo si "Hospital" yio lo gba abere arun Ponju-Ponju Dokita to wa nibe yio fi owo si iwe re wipe o ti yege ninu eleyi pelu. Lehinna wa tun lo si ibikan ninu Hosiptal, wa tun lo si odo Dokita omiran, iyen na yio tun fun ni abere miran m efa, ti o ba gba awon abere yi tan. Dokita na yio fi owo si wipe oluware yege. Awon abere yi duro fun ki sisopena ma ba oluware ja, ati awon arun kekemiran.

Lehin eleyi wa wa lo san owo fun awon oloko Ofurufu, sugbon ti o ko ba fe wahala lati se, bi o ba lo ba Alhaji Kafo tabi Nigeria Zumratul Hujaj won yio ran oluware lowo nipa ati san owo Oko ofurufu. won kosi ni gba kobo le lowo re si iye ti awon Oloko ofurufu yio gba. Ti o ba ti san owo beni won yio fun oluware ni iwe lati odo awon Oloko Ofurufu wipe iye bayi lo san. Bi owo ba po lowo oluware, awon mejeji ti mo wi yi le gba oluware ni imoran wipe ki oluware ma wa da owo Oko Ofurufu yi ni die-die tit owo re yio fi pe. Bi oluware ba nda owo yi die-die, beni won yio ma gba iwe fun oluware lati odo awon Oloko Ofurufu wipe owo re di iye bayi-bayi ti o da.

Bi oluware ba fe wo Oko Ofurufu lati Eko "Lagos" oluware yio san "£164 7. 6" Iyen ni wipe oluware ti san owo Oko Ofurufu lati Eko lo si Jida ati owo Oko Ofurufu lati Jida lo si Medina. awon Oloko Ofurufu yio si tun gbe oluware pada lati Medina wa si Jida, ati Jida pada si Eko "Ikeja" oluware si ti san owo ori Oba Meka mo owo ti oluware san fun awon Oloko Ofurufu yen, awon ni won yio san owo ori oluware ni Jida. Ti o ba je wipe lati Kano lo wun oluware lati fo ni, oluware alo san £146. 1. 6. ninu owo yi. oluware ti san owo Oko alo ati abo de Jida at owo Oko Ofurufu de Medina ati owo ori Oba Meka pelu.

(Ko ti pari)

# Elulu Lo r'ojo Parare

**Ni ojo kan, aroni fun Elulu ni ado kan pe, bi o ba sa ti si ado na, ojo ni lati bere si ro. Ni akoko osupa ti awon eranko fe jagbo, Elulu fa ojo nla kan fun won.**

**Nigbati ojo na nro olukuluku eiye ati eranko lo ko wo ile won lo. Sugbon Elulu gbagbe pe on ko mo ile ko. Lehin ti ojo pa a daradara, otutu mu, o si bere si gbon.**

**Nwon ni ki nwon lo pe Osanyin wa bi o ti de, o ni ha! Elulu, iwo lo fa ojo para re.**

## OLE TO JA BODE OBA EWA ODUN MARUN.

EKO. Rafiu Agoro. Ajibade Hassan ati Bello Owolabi ni awon enia meta to dimopo lo ji Apoti aso mejidinlogbon ni Bode Oba ni Apapa.

Nigbati owo Olopa te won, nwon ro'jo enu won patapata, agbare-gbabo, adajo ni ki enikokan won lo gbewa logba ewon fun odun marun-marun pelu ise aseon.


ARADAN NERVIGORA

Oni u ese pataki fun imarale gba [illegible] areno ipe fun awon alaya pupo. O dara fun [illegible], eje dudu, isokun oju, [illegible] owo, ailetun, ailokun ninu ati [illegible] bawonni. O je ajidew fun awon ti agbara won ndinku. On na [illegible] yi lo ti o ti d "Afeju ku [illegible]." 5/6d. pere pelu owo oko 1/6d c. [illegible] 7/- Post Free.

The Egba Trading Aradan Stores 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.





# Ajodun Ominira Ara Malaya



Opo ti a nwo ti o duro ninu aworan yi ni eyiti o mbe ni Trafalgar Square nilu Oyinbo, legbe re ni ile awon ara Malay gbe wa. Asia ti nwen ta yi niti awon ara ile Malay ni asiko ti nwon nse ajodun ominira ile won. Oruko Prime Minister ile na nje Tunku Abudu Rahman.

## AWON OMO ILE NIGERIA NILU OYINBO



**Awon meta ti a nwo yi ni awon omo akeko meta ti o lo ko eko ni Royal College of Science and Technology Glasgow, Scotland. Eni ti o mbe ni owo osi ni oruko re nje Babatunde Adekunle Olanrewaju Fisher. Awon meteta mba ara won jiroro.**

Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28 Kosoko Street, Lagos, P.O. Box 467 Phone 23370